# Ìfètòsọmọ bíbí ògùn oníkóró

## Ògùn oníkóró tó wà fún Enití ó ń fún ọmọ lóyàn



**Àlàyé nípa rẹ̀:**

- Ògùn oníkóró jẹ́ ọ̀kan nínú gbogbo ìfètòsọ́mọ bíbí oníkóró.
- Ó gbọdọ̀ lo ẹyọ̀kan lójojúmọ́
- Ó lè fa kí ǹkan oṣù ma ṣe ségesège ní oṣù díè àkọ́kọ́ tàbí kí ó má wa rárá.
- Ko léwu fún obìnrin tí ó ń fún ọmọ lọ́yàn. Obìnrin lè bẹ̀rẹ̀ ògùn náà ní kété tí o bá bímọ
- Kò léwu fún obìnrin tí ó ní àrùn HIV tí ò sì ń lo ògùn re. Bá elétò ìlera rẹ sọ̀rọ̀

**Bí ó ti lè dènà oyún sí:**

- Ní lílò fún ọdún kan àkókò, óseése kí ó dín díè ní ẹyòkan nínú ọgórun obìnrin kí ó lóyún 1 % (oyún kan nínú ọgórun obìnrin).
- Sùgbọ́n tí ó bá tàsé, ó seése kí ódín díè ní mẹ́ta sí mẹ́wàá ọgọ̀run obìnrin kí ó lóyún (3-10%)

**Bí óse ń ṣiṣẹ́:**

- Lo kóró kan  ní ojojúmọ́ ní àkókò kan náà.

- Ògùn náà ní èròjà ara (progestin) nínú tí yíò mú ikun tí ówà ní enu ọ̀nà ilé ọmọ kí ó ki, èyí yí ò dènà kí àtò okùnrin má lè wọ ilé ọmọ.
- Ògùn náà kì jẹ́ kí obìnrin yé ẹyin tí ópọ́n ní oṣoosù

**Àkíyèsí pàtàkì:**

- Ànfàání wà láti dá dúró ní ìgbà kugbà tí a bá fẹ́ láti lóyún lái ní lò láti rí akọ́ṣẹmọ́ṣẹ ìfètòsọ́mọ bíbí.
- Kò fa ìdíwọ́ kankan fún ìbálòpọ̀ lọkọ laya
- Oní láti rántí lo ògùn oníkóró lẹ́ẹ̀kan lójúmọ́ ní àkókò kan náà.
- Kọ̀ dènà àrùn ìbálòpọ̀ tàbí HIV.

**Àànfàní:**

- Kò léwu fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ obìnrin àti pé ọjọ́ orí obìnrin kò dí lílò rẹ̀ lọ́wọ́
- Ó ń sisẹ́ dáradára bí a bá lòó dédé.
- Kò dá omi ọyàn laamu
- Kì sáábà fa ẹ̀fọ́rí tàbi ìfunpá gíga.

**Bá akọ́ṣẹmọ́ṣe ìfètòsọ́mọ bíbí sọ̀rọ̀ bí:**

- O bá ní ìfunpá gíga tàbi àrùn tí ó níse pẹ̀lu ọkàn, ẹ̀jẹ̀ tàbi ẹ̀dọ̀fóró.
- O bá ní kókó nínú ọyàn (jejere) tàbí ẹnikéni nínú ẹbí rẹ ti ní kókó nínú ọyàn rí.
- Nǹkan ọmọbìrin rẹ bá ń sẹ̀jẹ̀ láímọ̀ ìdí rẹ̀

Get it together
KNOW. TALK. GO.



**Bí aṣe lè lò ó:**

- Bèrè láti orí kóró àkọ́kọ́ nínú àpò rẹ lóòní lẹ́yìn tí o tí se àyẹ̀wò pé kò sí oyún.
- Lo kóró kan lójojúmọ́ títí tí o fi lo èyí tí ówà nínú àpò náà tán .
- Lo kóró náà ní ojojúmọ́ ní àkókò kan náà.
- Tí o bá bì láàrín wákàtí méjì sí ìgbà tí o lòó, mu kóró òmíràn kíákíá, kí osì máa tèsíwájú lílò rẹ̀
- Ìgbẹ́ gburu (mẹ́fà sí mẹ́jọ ní wákàtí mẹ́rìnlélógún) túmọ̀ sí wípé ògùn oníkóró yìí kò ní sisẹ́ dáradára
- Ri dájú pé oní àpò míràn lọ́wọ́ kí o tó lo àpò ọjọ́ 28 tán.
- Bí ó bá jẹ́ ilé ìta ògùn lo ti ràá, ka ìwé pelebe tí ó wà ní inú ògùn náà.

**Padà lọ sí ilé ìwòsàn tí o bá:**

- Ní ìbéèrè tàbi idoju kankan.
- Pa kóró mẹ́ta jẹ tí o sì ti ní ìbálòpọ̀ ní ọjọ́ márun séyìn, tí o kò sì fẹ́ láti lóyún
- Ní alieere tí ó jẹyo
- Lérò pé oti lóyún

## Àkíyèsí:

***Tí o bá ti lo àpò ògùn kan tán, ri dájú pé o bẹ̀ẹ̀rẹ̀ àpò kejì ní ọjọ́ kejì láì pa ìkankan jẹ.***

**Tèlẹ́ ìlànà wọ̀nyí tí o bá pa ọjọ́ kan je tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ:**

| Bi o bá: | Kí o: |
|---|---|
| Pa ọjọ́ kan tàbí méjì jẹ | • Lo ògùn kan ní kètà tí o bá rántí<br>• Kí o sì ma lo ìyókù lo ní déédé, àkókò tí o tín babọ̀ (Ótúmọ sí pé ó seése kí olo méjì ní ọjọ́ kan tàbí ní àkókò kan |
| Pa ọjọ́ mẹ́ta tàbí ju béè lo jẹ ní ọ̀sẹ̀ àkọ́kọ tàbí ìkejì ní ìyípo kan, tàbí:<br>Bí ó bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀ẹ̀rè àpò kan tàbí míràn lẹ́yin ọjọ́ mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ | • Yára lo ògùn kóró kan<br>• Lo Ìlànà míràn (rọ́bà ìdábòbò) tàbí kí o má ba okùnrun lòpọ̀ fún ọjọ́ méje<br>• Bí o bá si ní ìbálòpọ̀ fún ọjọ́ márun, yára lo ìfètòsọ́mọ bíbí pàjáwìrì (wo ìwé pélébé ìfètòsọ́mọ bíbí pàjáwìrì) |
| Bí o bá pa kóró mẹta jẹ ní ọ̀sẹ̀ kẹ́ta ní ìyípo kan | • Yára lo ògùn kóró kan<br>• Ri wípé o lo gbogbo ògùn èyí tí a fi èròjà ara se tán, tí ó jẹ́ àpò oní 28, dá àwọn ògùn méje tí akò fi èròjà ara se nù<br>• Bẹ̀ẹ̀rè àpò tuntun míràn ní ọjọ́ kejì<br>• Lo ìlànà míràn (rọ́bà ìdábòbò) tàbí kí o má ba okùnrin lòpọ̀ fún ọjọ́ méje<br>• Bí o bá si ní ìbálòpọ̀ fún ọjọ́ márun, yára lo ìfètòsọ́mọ bíbí pàjáwìrì (wo ìwé pélébé ìfètòsọ́mọ bíbí pàjáwìrì) |
| Bí o bá pa ọ̀kọn kan nínú kóró tí a kò fi èròjà ara se jẹ (kóró méje tí ó gbéyìn nínú kóró 28 nínú àpò | • Da àwọn ògùn tí a kò fi èròjà ara se tí o pajẹ nù<br>• Lo ògùn ìyókù parí kí o sì bẹ̀ẹ̀rè àpò / pali míràn |

Get it together
KNOW. TALK. GO.

NURHI 2
NIGERIAN URBAN REPRODUCTIVE HEALTH INITIATIVE